William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

William R. Bascom
Northwestern University

# Ilana Isin fun gbigba Ibukun sori Igbeyawo Ibile

*Ọkunrin ati Obirin na yio duro niwaju Tabili Oluwa, Alufa yio si sọ bayi fun wọn:—*

ENYIN ntọrọ adura Ijọ fun Ibukun Ọlọrun sori igbeyawo nyin, o tọ ki a ran nyin leti pe, fun Onigbagbọ igbeyawo ko wà fun kiki ati tẹ ifẹ ara lọrun, tabi lati bimọ nikan, ṣugbọn ni pataki fun ajumọ ran ara ẹni lọwọ ati lati tu ara ẹni ninu, ninu ipọnju ati ninu irọra. Ati pẹlu o yẹ ki ẹ ranti pe Oluwa wa kọ wa pe Igbeyawo titi iku yio fi ya awọn ti o gbeyawo ni, nitoripe nigbati a bi i lere niti ikọsilẹ, o dahun pe "Ẹnyin ko ti ka a pe, ẹniti o da wọn nigba atetekọṣe, o da wọn ti akọ ti abo? O si wipe, nitori eyi li ọkunrin yio ṣe fi baba ati iya rẹ silẹ, yio famọ aya rẹ, awọn mejeji a si di ara kan, nitori nwọn, ki iṣe meji mọ bikoṣe ara kan. Nitorina ohun ti Ọlọrun ba so ṣokan, ki enia ki o maṣe ya wọn. Nwọn si wi fun u pe, Eṣe ti Mose fi aṣẹ fun wa wipe, ki a fi iwe ikọsilẹ fun u, ki a si kọ ọ silẹ? O wi fun wọn pe, nitori lile aiya nyin ni Mose ṣe gba fun nyin lati mā kọ aya nyin silẹ; ṣugbọn lati igba atetekọṣe wa ko ri bẹ. Mo si wi fun nyin, ẹnikẹni ti o ba kọ aya rẹ silẹ, bikoṣepe nitori agbère, ti o si gbe omiran ni iyawo, o ṣe panṣaga; ẹnikẹni ti o ba si gbe ẹniti a kọsilẹ ni iyawo, o ṣe panṣaga."

*(Matt. 19: 4—9).*